# Awọn Ilé-iwé Ijọba Ti Agbegbe Baltimore

# Àwọn Ètò Ilé-iwé Alákọ̀ọ́bẹrẹ ti Magnet

**Fi ìwé ìbéèrè fún tìrẹ kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ Ojú Òpó BCPS Magnet (tinyurl.com/BCPSMagnet)**




## Ọjọ́ Ibéèrè Fún Tí Ó Kẹ́yìn:

## ỌJỌ́ ẸTÌ, NOVEMBER 6, 2020

Gbogbo ìbéèrè fún ni a gbọ́dọ̀ gbé kalẹ̀ ní déètì tí ó wà lókè yìí

**Fi ìwé ìbéèrè fún tìrẹ kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ tinyurl.com/BCPSMagnet**
**láti aago méjìlá ọ̀sán, September 16, 2020, títí da aago kan ọ̀sán ní November 6, 2020**

Síkáànì ibí yìí láti béèrè fún lórí ẹ̀rọ àbí kí o gbà ìwé ìbéèrè fún kan lórí ẹ̀rọ.

Jọ̀wọ́ mú àtẹ̀jáde yìí dání gẹ́gẹ́ bí ohun ìtọ́kasí títí gbogbo àkókò ìbéèrè fún.

Ìgbésẹ̀ 1

**Fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ kà gbogbo ìfitónilétí inú àtẹ̀jáde náà ṣáájú dídáhùn àwọn ìbéèrè inú ìwé ìbéèrè fún yìí.**

**A lè ṣe àfikalẹ̀ ìbéèrè fún lórí ẹ̀rọ títi da aago kan ọ̀sán ní November 6, 2020.**

# Àwọn Ìbéèrè Àtìgbàdégbà

**Kín ni àwọn ètò magnet?**
Àwọn ètò Magnet jẹ́ èto tí o fi ojú sun ìsọ̀rí tí a gbọ́dọ̀ wọlé sínú rẹ̀ nípasẹ̀ ìgbésẹ̀ ìbéèrè fún ti magnet. Wọ́n n pèsè àwọn ìrírí tí ó jinlẹ̀ àti ìyàn tí ó yè kooro fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ní oríṣìí ìfẹ́, ẹ̀bùn, àti orí pípé. Gbogbo ètò magnet ni ó kún ojú òṣùwọ̀n àwọn àmúyẹ ti Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Agbègbè Baltimore fún ìgbéga àti ìkẹ́kọ̀ọ́jáde.

**Tani ó lè béèrè fún wíwọ̀ ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ètò magnet?**
Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó lẹ́tọ̀ọ́ láti lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìjọba ti Agbègbè Baltimore lè béèrè fún un. *Jọ̀wọ́ kíyèsí àwọn gbèdéke tí ó dá lórí gíréèdì (see page 3).*

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí kò nílé ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún ètò magnet gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ míràn yòó wù ti ní.

**Ṣé mo lè yàn ju ètò magnet kan lọ nínú ìwé ìbéèrè fún náà?**
Bẹ́ẹ̀ni. Jọ̀wọ́ ṣe àfikalẹ̀ ìwé ìbéèrè fún KAN péré fún olùbéèrè kan. O lè yàn tó ètò magnet méta (3) nínú ìbéèrè fún náà. Jọ̀wọ́ fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ sàmì sí (àwọn) ohun tí o yàn. Jọ̀wọ́ kíyèsí àwọn gbèdéke tí ó dá lórí gíréèdì. *(see page 3).*

**Ṣé mo lè fi ìbéèré fún mi ránṣẹ́ nípasẹ̀ ímeèlì àbí fáàsì?**
Bẹ́ẹ̀kọ́. Gbogbo ìbéèrè fún ni a ó **fi kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ ní aago kan ọ̀sán** ní November 6, 2020, nípasẹ̀ ìlànà ìbéèrè orí ẹ̀rọ magnet.

**Báwo ni màá ṣe mọ̀ pé a ti rí ìwé ìbéèrè fún mi gbà?**
Àwọn tí ó kọ̀wé béèrè fún lórí ẹ̀rọ yóò gbà èsì pé a ti ríi gbà nípasẹ̀ ímeèlì. Fún ìfidímúlẹ̀ àwọn ìbéèrè fún tí a fi ránṣẹ́ nípasẹ̀ ilé ìfìwéránṣẹ́, a rọ àwọn òbí gidigidi láti ṣe ìfiránṣẹ́ ìwé ìbéèrè fún náà **nípasẹ̀ ìwé tí ó ní ẹ̀rí — a béèrè risiiti tí wọ́n dá padà**.

**Ṣé mo lè ṣe àyípadà sí (àwọn) ètò tí mo yàn?**
Àyípadà **YÒÓWÙ** nínú (àwọn) ètò tí o yàn ni o GBỌ́DỌ̀ ṣe ní aago kan ọ̀sánlórí ẹ̀rọ ní òpin ọjọ́ ìbéèrè November 6, 2020.

**Lọ́wọ́lọ́wọ́, orúkọ mi wà lára àwọn tí ó n wọ̀nà fún ètò ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti magnet, ṣé mo tún lè kọ̀wé béèrè fún nígbà keji?**
Gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ tí ó fẹ́ wọlé sínú ètò magnet fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021–2022, títí dórí àwọn tí orúkọ wọn wà nínú àwọn tí ó n wọ̀nà fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2020–2021, gbọ́dọ̀ béèrè fún. *Jọ̀wọ́ kíyèsí àwọn gbèdéke tí ó dá lórí gireedi. (see page 3).*

**Ṣé àwọn ẹ̀gbọ́n àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ètò magnet máa n gba àmójútó àrà ọ̀tọ̀?**
Fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ni a n fún àwọn ọmọ jẹ́léósinmi tí ó ní ẹ̀gbọ́n tí ó jẹ́ pé **lọ́wọ́lọ́wọ́ ó wà nínú irú ètò magnet kan náà** tí yóò sì **tẹ̀ síwájú** nínú ètò magnet yẹn nínú ọdún tí ọmọ jẹ́léósinmi tí ó fẹ́ wọlé náà ń wá ọ̀nà láti wọlé (*see page 5 of this brochure for details*). Bí bẹ́ẹ̀kọ́, ìwé ìbéèrè fún kọ̀ọ̀kan ni à ń ṣiṣẹ́ lórí rẹ̀ lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ tí ó sì jẹ́ wípé àwọn ẹ̀gbọ́n, títí dórí àwọn tí a bí papọ̀, tí ó n béèrè fún irú (àwọn) ètò magnet kan náà kìí gba ìgbàwọlé ṣáájú.

**Ṣé ìdánwò magnet wà?**
Kò sí ìdánwò magnet fún àwọn tí ó ń béèrè fún ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àwọn tí ó ń béèrè fún gbọ́dọ̀ ní ẹ̀tọ́ láti lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìjọba ti Agbègbè Baltimore ní àkóko ìbéèrè fún.

**Báwo ni a ti ń yàn àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fún ìgbàwọlé?**
**Àwọn ààyè tí ó bá wà nílẹ̀ ni a ó dí ṣáájú** pẹ̀lú àwọn ìgbàwọlé ti ìṣáájú. Ń ṣe ni a máa ń fi tẹ́tẹ́ dí àwọn ààyè tí ó bá kù àti láti kọ orúkọ àwọn tí ó ń wọ̀nà. *(Wò Superintendent's Rule 6400: Magnet Programs fún àfikún ìfitónilétí.)*

**Báwo àti nígbà wo ni a ó fi tó mi létí nípa ibi tí ọ̀rọ̀ ìgbàwọlé mi dé?**
A ó wífún àwọn òbí nípasẹ̀ í-meèlì nípa ti ìpinnu ìgbàwọlé. A ó pèse àwọn ìpinu Magnet ní February 5, 2021. *(deeti náà lè yí padà).*

## Ìfitónilétí Nípa Ìgbaniwọlé

Ìbéèrè fún ti ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ètò magnet yóò wà ní àrọ́wọ́tó lórí ẹ̀rọ nípasẹ̀ (tinyurl.com/BCPSMagnet) bẹ̀rẹ̀ láti aago méjìlá ọ̀sán ní September 16, 2020. Àwọn ìbéèrè fún **gbọ́dọ̀** di fífi kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ ní aago kan ọ̀sán ní **November 6, 2020**.

A ń ṣe ìgbésẹ̀ ìgbàwọlé magnet ní ìbámu pẹ̀lú Superintendent's Rule 6400: Magnet Programs. A rọ àwọn òbí gidigidi láti fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ ṣe àtúnyẹ̀wò Superintendent's Rule 6400 àti gbogbo ohun èlò ìbéèrè fún. Ṣáájú ìfikalẹ̀ ìbéèrè fún, a rọ àwọn òbí láti wá síbi nínú Ìpàdé Àlàyé Ìbéèrè àti àtúnyẹ̀wò àlàyé fún ètò kọ̀ọ̀kan tí o fẹ́

Àwọn tí ó lẹ́tọ̀ọ́ láti lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìjọba ti Agbègbè Baltimore fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022 ni a ń fi tẹ́tẹ́ àpapọ̀ yàn fún ìgbàwọlé.

Àwọn tí ó béèrè fún tí kò bá kún ojú òṣùwọ̀n ọjọ́ orí ìwọlé jẹ́léósinmi fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022 gbọ́dọ̀ kún ojú òṣùwọ̀n ìtètè wọlé. Ẹ̀dà lẹta tí o fi béèrè fún ìdánwò ìtètè wọlé sí jẹ́léósinmi ni a gbọ́dọ̀ fisórí ẹ̀rọ pẹ̀lú ìbéèrè magnet. *(See page 5 of this brochure for additional information.)*

Jọ̀wọ́ ṣe àfikalẹ̀ ìwé ìbéèrè fún KAN péré fún olùbéèrè kan. YO lè yàn tó **ètò magnet méta** (3) nínú ìbéèrè fún náà. Jọ̀wọ́ kíyèsí àwọn gbèdéke tí ó dá lórí gireedi. *(See page 3.)*

**Gbogbo ìbéèrè fún ni a gbọ́dọ̀ fàkalẹ̀ lórí ẹ̀rọ ní November 6, 2020.**

**Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rí ààyè láti wo Special Education, àti iṣẹ́ àtilẹ́yìn Abala 504 ní gbogbo ilé-ìwé tí ó ní ètò magnet.**

**Àyípadà YÒÓWÙ nínú (àwọn) ètò tí o yàn ni o GBỌ́DỌ̀ ṣe lórí ẹ̀rọ ní aago kan ọ̀sán ní November 6, 2020**

Àwọn ìbéèrè fún gbọ́dọ̀ **di fífi kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ ní aago kan ọ̀sán ní November 6, 2020**

# Àwọn Ètò Ilé-iwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Magnet

**Àfikún ìfitónilétí nípa ètò wà ní àrọ́wọ́tó https://bcpsonlineapplication.com/apply/.**

## Ìgbésẹ̀ 2

## Ka àwọn ìjúwe ètò ìsàlẹ̀ yìí láti mọ (àwọn) ètò magnet tí ó bá ìfẹ́ ọmọ rẹ mu jùlọ

**Kò sí ìdánwò magnet fún àwọn tí ó ń béèrè fún ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ètò magnet. Àwọn tí ó lẹ́tọ̀ọ́ láti lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìjọba ti Agbègbè Baltimore ni a ń fi tẹ́tẹ́ àpapọ̀ yàn fún ìgbàwọlé.**

### Ètò Ọdún Àkọ́kọ́ Digiri Àgbáyé

***Wellwood International School***
***Pikesville 21208***
*A gbà ìbéèrè fún fún Gireedi K - 2*

***Woodmoor Elementary School (IB candidate school)***
***Gwynn Oak 21207***
*A gbà ìbéèrè fún fún Gireedi K - 2*

Gẹ́gẹ́ bí ara Ètò Ọdún Àkọ́kọ́ Digiri Àgbáyé tí a mọ̀ káàkiri àgbáyé, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣàmúgbòrò mímọ orísìí àṣà wọn sì fọkànsí níní ìrirí àgbáyé nípasẹ̀ ẹ̀kọ́ kókó iṣẹ́ ààyò tówọra mẹ́fà tó dá lórí bíbèrè tó lágbára. Àwọn kókó wọ̀nyí ni a kọ́ sínú gbogbo àkóónú a sì ṣàmúlò wọn káàkiri àgbáyé sí àwọn àṣà,èyí ń ṣe kórí fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti jẹ́ kí ayé tó yí wọn ká mọ́gbọ́nwá nípasẹ̀ ìrírí àkọ́ọ́. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ń kópa nínú àwọn iṣẹ́ ìṣe èyítí ń ṣe kóríyá fún ìmọ̀ àgbáyé wọn, wọn sì ń kópa nínú ìmúdàgbà ìbánisọ̀rọ̀ ti èdè Faranse ní Wellwood International àti èdè Sipaniṣi bí Woodmoor Elementary. .

### S.T.E.A.M.

***Chatsworth School***
***Reisterstown 21136***
*A gbà ìbéèrè fún fún Gireedi K - 2*

***Cromwell Valley Elementary Magnet School***
***Towson 21286***
*A gbà ìbéèrè fún fún Gireedi K - 2*

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ń dàgbà nínú iṣẹ́ kíkọ́ ìgbàlódé títí dórí ìbánisọ̀rọ̀, ìfọwọ́sowọ́pọ̀, orí pípé, àti ohun àfọwọ́ṣe nínú ètò ikẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń pa ìkọ́ni BCPS, S.T.E.A.M papọ̀. (ìmọ̀ ìjìnlẹ̀, ìmọ̀ ẹ̀rọ, iṣẹ́ ẹ̀rọ, ọnà, àti ìṣirò), àti ìmọ̀ ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá. Nínú àyíká tí ó dá lórí iṣẹ́ àkànṣe, tí ènìyàn ń dá sí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ń ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ òye ayé nípa gbígba ọ̀nà tí ó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ abala tí a fi ojú rè sun ohun tuntun àti yíyanjú ìṣòro. Gẹ́gẹ́ bí ara ètò wíwọnú ìmọ̀ ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá, a ró àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lágbára láti di ẹni tí ó ń pèsè ìfitónilétí bí wọn ti ń kọ kóòdù tí wọn sì n ní ìfaradà láti yanjú ìṣòro.




**Oṣù Àwọn Ilé-ìwé Magnet Ní Orílẹ̀-èdè– February 2020**
*BCPS Magnet Poster Contest*
***Yumi D., Grade 4***
***Cromwell Valley Elementary Magnet***

### Fífi Gbígba Ẹ̀gbọ́n Wọlé Ṣáájú

Ó bá àwọn ọmọ jẹ́léósinmi tí ó béèrè fún <u>ṣáájú</u> fífi tẹ́tẹ́ yàn fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022 NÌKAN

Fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ni a n fún àwọn ọmọ jẹ́léósinmi tí ó ní ẹ̀gbọ́n tí ó wà nínú irú ètò magnet kan náà lọ́wọ́ lọ́wọ́ tí yóò sì tẹ̀ síwájú nínú ètò magnet yẹn nínú ọdún tí ọmọ jẹ́léósinmi tí ó fẹ́ wọlé náà ń wá ọ̀nà láti wọlé. Fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ni a máa ń ṣe ṣáájú ìgbésẹ̀ fífi tẹ́tẹ́ yàn.

Kí ènìyàn tó lè kún ojú òṣùwọn ti fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ní ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021–2022, a gbọ́dọ̀ ṣe ìfikalẹ̀ ojúlówó ìbéèrè fún ọmọ jẹ́léósinmi tí ó fẹ́ wọlé náà ní Ètò BCPS Magnet ní ọjọ́ tí ìbéèrè fún bá pé, **November 6, 2020**. A gbọ́dọ̀ fi orúkọ ẹ̀gbọ́n, gíréèdì tí ó wà, àti ètò ilé-ìwé sínú ìwé ìbéèrè fún náà.

**Wo See Superintendent's Rule 6400 fún àfikún ìfitónilétí.**

# Ìfitónilétí Ọkọ̀ Wíwọ̀ ti Magnet

**Wíwọlé sínú ètò magnet kò fi dáni lójú pé Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Agbègbè Baltimore yóò pèsè ọkọ̀ wíwọ̀.**

## Ìgbésẹ̀ 3

**Ka ìfitónilétí ìsàlẹ̀ yìí láti mọ̀ bóyá ọmọ rẹ lẹ́tọ̀ọ́ sí ọkọ̀ wíwọ̀ lọ sí ètò magnet kan ní pàtó.**

**Chatsworth School**
222 New Avenue
Reisterstown 21136 • (410) 887-1103
A pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a pín láti lọ sí Àwọn Ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Cedarmere, Franklin, Glyndon, Owings Mills, Reisterstown, àbí Timber Grove.

Cromwell Valley Elementary Magnet School
825 Providence Road
Towson 21286 • (410) 887-4888
A pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a pín láti lọ sí Àwọn Ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Halstead Academy, Hampton, Oakleigh, Pleasant Plains, Rodgers Forge, Stoneleigh, Villa Cresta, àbí West Towson.

Wellwood International School
2901 Smith Avenue
Pikesville 21208 • (410) 887-1212
A pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a pín láti lọ sí Àwọn Ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Bedford, Fort Garrison, Milbrook, Summit Park, Wellwood, àbí Winand

Woodmoor Elementary School
3200 Elba Drive
Gwynn Oak, 21207 • (410) 887-1320
A pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a pín láti lọ sí àwọn ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Arbutus, Baltimore Highlands, Bedford, Catonsville, Chadwick, Church Lane, Deer Park, Dogwood, Edmondson Heights, Featherbed Lane, Halethorpe, Hebbville, Hernwood, Hillcrest, Johnnycake, Lansdowne, Lyons Mill, Milbrook, New Town, Powhatan, Randallstown, Relay, Riverview, Scotts Branch, Westchester, Westowne, Winand, Winfield, Woodbridge, Woodmoor àbí Woodholme

### Ìgbàlejò Àwọn Ilé-ìwé Agbègbè Baltimore Àwọn Ètò Ilé-iwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Magnet

Ó yẹ kí a ro ti ibi tí a ń gbé àti ọ̀rọ̀ ọkọ̀ wíwọ̀ nígbà tí a bá ń béèrè fún àwọn ètò magnet.




**Jọ̀wọ́ Rántí:** ***Wíwá déédé àti lákòókò ni a ń retí láti ọwọ́ gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ tí ó fi orúkọ sílẹ̀ nínú àwọn ètò magnet.***



## ỌKỌ̀ WÍWỌ̀

Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Agbègbè Baltimore ń pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ lọ àti padà láti ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ètò magnet fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń gbé ní ẹkùn ìwọkọ̀ ti ètò magnet. A ṣètò lílọ-bíbọ̀ àwọn ọkọ̀ kan lati ilé. Èyí lè nílò pé kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọ ọkọ̀ àdúgbò tí ó ń rìn déédé àbí láti rìn lọ sí ilé-ìwé ti ilé, níbi tí a ti gbé wọn tí a sì wà wọ́n lọ sí ibi ètò magnet.

Àwọn ilé-ìwé yóò fi tó àwọn òbí létí nípa àwọn ìlànà ọkọ̀ wíwọ̀ kí a tó ṣí ilé-ìwé.
**Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Agbègbè Baltimore kìí pèsè ọkọ̀ wíwọ̀ ní àwọn ibi tí kò sí ní ẹkùn ọkọ̀ wíwọ̀ ti ètò magnet.**

# Ìfitónilétí Jẹ́léósinmi

## Títètè Gbani Wọlé Síbi Ìdánwò Jẹ́léósinmi

Ní àkókò ìbéèrè fún, àwọn jẹ́léósinmi tí ó ń béèrè fún gbọ́dọ̀ kún ojú òṣùwọ̀n Ọjọ́-Orí-Ìwọlé ti Ìpínlẹ̀ Maryland fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021–2022 (Ọmọ Ọdún Márùn ní September 1, 2021) àbí wọ́n ti gbọ́dọ̀ ti béèrè ní ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ wọn tí a ti tò sí ẹ̀kùn kan fún ìtètè gbà wọlé síbi ìdánwò jẹ́léósinmi.

A lè da ọ̀rọ̀ ọmọ kan rò fún ìtètè gbà wọlé síbi ìdánwò jẹ́léósinmi fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022 (Ọmọ ọdún márùn ní September 1, 2021 àti ní ṣáájú àbí October 14, 2021.

Láti ṣètò ìtètè gbà wọlé síbi ìdánwò jẹ́léósinmi, àwọn òbí gbọ́dọ̀ ṣe àfikalẹ̀ lẹta fún ọ̀gá ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ wọn tí a ti tò sí ẹ̀kùn kan ní November 6, 2020. Nínú lẹta náà ni ó yẹ kí a ti rí ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ orúkọ ọmọ náà àti deeti tí a bíi, pèsè ìfitónilétí bí a ti lè kàn síni fún òbí, béèrè àkókò fún ìdánwò ní January 2021, kí o sì ṣàlàyé pé ń ṣe ni òbí náà ń béèrè fún èto ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti magnet kan. (Wo àpẹẹrẹ lápá ọ̀tún.)

Àwọn òbí **GBỌ́DỌ̀** fi **ẹ̀dà** lẹta kó sí sórí ẹ̀rọ tí ó ń béèrè fún ìtètè gbà wọlé síbi ìdánwò jẹ́léósinmi **pẹ̀lú ìbéèrè fún ti magnet wọn**.

Wo Early Childhood Parent Guidelines for applying for early admission to kindergarten. (www.tinyurl.com/BCPSEarlyChild)

### ÀPẸẸRẸ LẸTA

Adirẹsi Òbí
Deeti: ___/___/2020

Orúkọ Ọ̀gá Ilé-ìwé
Ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí a ti tò sí Ẹkùn
Àdirẹsi Ilé-ìwé

Ọ̀wọ́n *(orúkọ ọ̀gá ilé-ìwé):*

Mo n kọ̀wé láti béèrè àkókò kan fún ìdánwò ìtètè gbà wọlé fún ọmọ mi, (ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ orúkọ), (déètì tí a bíi). Mo ń béèrè pé kí ìdánwò náà wáyé ní January 2021, bí mo ti tún ń béèrè fún pé kí ọmọ lè lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ètò magnet fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022.

Mo ń wọ̀nà láti gbọ́ láti ọ̀dọ̀ yín nípa àkókò tí a yàn fún ọmọ mi fún ìdánwò ìtètè gbà wọlé sí jẹ́léósinmi. A lè kàn sí mi ní (nọ́ḿbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀) àbí (àdírẹ́sì ímeèlì).

Nítòótọ́
Ìbọwọ̀lù Òbí

## Fífi Gbígba Ẹ̀gbọ́n Wọlé Ṣáájú

(Ó bá àwọn ọmọ jẹ́léósinmi tí ó béèrè fún ṣáájú fífi tẹ́tẹ́ yàn fún ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021-2022 NÌKAN)

Fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ni a ń fún àwọn ọmọ jẹ́léósinmi tí ó ní ẹ̀gbọ́n tí ó wà nínú irú ètò magnet kan náà lọ́wọ́ lọ́wọ́ tí yóò sì tẹ̀ síwájú nínú ètò magnet yẹn nínú ọdún tí ọmọ jẹ́léósinmi tí ó fẹ́ wọlé náà ń wá ọ̀nà láti wọlé. Fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ni a máa ń ṣe ṣáájú ìgbésẹ̀ fífi tẹ́tẹ́ yàn.

Kí ènìyàn tó lè kún ojú òṣùwọ̀n ti fífi ìgbàwọlé ẹ̀gbọ́n ṣáájú ní ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ 2021–2022, a gbọ́dọ̀ ṣe ìfikalẹ̀ ojúlówó ìbéèrè fún ọmọ jẹ́léósinmi tí ó fẹ́ wọlé náà ní Ètò BCPS Magnet ní ọjọ́ tí ìbéèrè fún bá pé, **November 6, 2020**. A gbọ́dọ̀ fi orúkọ ẹ̀gbọ́n, gíréèdì tí ó wà, àti ètò ilé-ìwé sínú ìwé ìbéèrè fún náà.

**Wò Superintendent's Rule 6400 for additional information (tinyurl.com/BCPSMagnet).**

**Wíwá déédé àti lákòókò ni à ń retí láti ọwọ́ gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ tí ó fi orúkọ sílẹ̀ nínú àwọn ètò magnet.**

**Àyípadà YÒÓWÙ nínú (àwọn) ètò tí o yàn ni o GBỌ́DỌ̀ ṣe online ní aago kan ọ̀sán ní òpin ọjọ́ ìbéèrè November 6, 2020**

**Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ẹ̀tọ́ sí Ẹ̀kọ́ Abirùn àti iṣẹ́ àtilẹ́yìn Abala 504 ní gbogbo ilé-ìwé tí ó ní ètò magnet.**

**Kàn sí BCPS Magnet Programs' Web site (tinyurl.com/BCPSMagnet)**

**àbí pe (443) 809-4127 fún àfikún ìfitónilétí.**

**Àwọn Ìbéèrè Fún Ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti Magnet tí a gbà fún àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Agbègbè Baltimore yìí**

Ó yẹ kí a ro ti ibi tí a ń gbé àti ọ̀rọ̀ ọkọ̀ wíwọ̀ nígbà tí a bá ń béèrè fún àwọn ètò magnet.





**Àwọn Ètò Magnet ti BCPS**
**105 W. Chesapeake Avenue**
**Towson, Maryland 21204**

**(443) 809-4127**
**tinyurl.com/BCPSMagnet**


# Ìpàdé Ìfitóniléti Ìbéèrè Fún

## Kó nípa ìgbésẹ̀ ìbéèrè fún ti magnet!

**Saturday, September 26, 2020**
**Ọjọ́ Abámẹ́ta, September 26, 2020**
**Yan abala kan: 10 ààrọ̀ tàbí 1:00 ọ̀sán**

**TÀBÍ**

**Ọjọ́rú, September 30, 2020**
**Yan abala kan: 10 ààrọ̀ or 6:30 ọ̀sán**

**A ó ṣe àwọn ètò lórí ayélujára**
**Àwọn òbí le forúkọsílẹ̀ ní Ojúlé wẹ́ẹ̀bù Ètò BCPS Magnet (tinyurl.com/BCPSMagnet) láti gba ìfìwépè í-meèlì kan sí ìṣẹ̀lẹ̀ náà.**

**Àlàyé náà le yípadà èyí dá lórí àwọn ìhámọ́ tó jọmọ́ àrùn COVID-19. Jọ̀wọ́ tọ́kasí Ojúlé wẹ́ẹ̀bù Ètò BCPS Magnetfún àlàyé titun jùlọ (tinyurl.com/BCPSMagnet).**

## Fún àlàyé síwájú síi, jọ̀wọ́ wo àwọn Ojúlé wẹ́ẹ̀bù ilé-ìwé:

| Ilé-ìwé | Ojúlé wẹ́ẹ̀bù ilé-ìwé | Í-meèlì Ilé-ìwé |
|---|---|---|
| Chatsworth School | https://chatsworthes.bcps.org/ | Jade Johnson<br>jjohnson7@bcps.org |
| Cromwell Valley Elementary Magnet School | https://cromwellvalleyes.bcps.org/ | Cathy Thomas<br>cthomas4@bcps.org |
| Wellwood International School | https://wellwoodes.bcps.org/ | Katie Lugli<br>klugli@bcps.org |
| Woodmoor Elementary School | https://woodmoores.bcps.org/ | Brendan Penn<br>bpenn@bcps.org |

**Àwọn òṣìṣẹ́ Ilé Iṣẹ́ Magnet yóò wà ní àrọ́wọ́tó nínú Ìpàdé Àlàyé Ìbéèrè láti dáhùn àwọn ìbèrè nípa ìlànà ìbéèrè magnet tí o kò bá le kópa nínú Ìpàdé Àlàyé Ìbéèrè, jọ̀wọ́ kàn sí ilé-ìwé náà fún ìfitóniléti nípa ètò magnet rẹ̀.**

**O tún lè gba ìfitóniléti nípa ètò nípa kíkàn si https://bcpsonlineapplication.com/apply/ àbí nípa pípe Àwọn Ètò BCPS Magnet ní (443) 809-4127.**

**GBÓLÓHÙN ÀÌṢÈGBÈ:** Ìgbìmọ̀ Ẹ̀kọ́ ti Agbègbè Baltimore kìí ṣègbè nítorí ọjọ́ orí, àwọ ara, ààbọ̀ ara, akọ-n-bábo, ìrísí (pẹ̀lú ìhùwàsí) àpọ́n àbí ẹni tí ó ti gbéyàwó, orílẹ̀-èdè àbí èdè, ẹ̀yà, ẹ̀sìn, irú ìbálòpọ̀, ipò iṣẹ́ ológun, àbí nnkan míràn yòówù nínú àwọn ètò ẹ̀kọ́, iṣẹ́ rẹ̀ àbí ìgbanísíṣẹ́ bí a ti là á kalẹ̀ nínú òfin ìpínlẹ̀ àti ti àpapọ̀.